# ÀWỌN KÓKÓ ÒRÒ PÀTÀKÌ 10
## láti ìjábò IPCC tuntun

**Ẹgbẹ 1 - Ìpìlẹ̀ ìmọ̀ sáyẹ̀nsì ti ara**

### 1 ÀWỌN ÌYÍPADÀ ÀÌRÒTẸ́LẸ̀

**À n ní ìrírí ìrúfin láàrín àwọn ìyípadà ojú-ọjọ́ àdáyébá ti ìgbà àtijọ́. Àwọn ìyípadà yí yára, láìròtẹ́lẹ̀ fún ẹgbẹẹgbẹ̀rún ọdún àti wípé díẹ̀ nínu wọn kò se é yípadà.** Ìmóruṣi àgbáyé ti dé 1.1°C ní ọdún méwàá tó kọjá [2010-2019] ní síse àkàwé sí àkókò ìṣáájú-iṣẹ́ [1850-1900]. Ìwọ̀n gáàsì CO2 ní ojú-afẹ́fẹ́ ti wà ní ìpele tó ga jùlọ ní ó kéré jù ọdún ẹgbẹ̀rún lọ́nà ẹgbẹ̀rún méjì.

### 2 OJÚSE ÈNÌYÀN

**Ipa ènìyàn kó ìdá ogórùn-ún nínú ìmóruṣi àgbáyé tí a ṣe àkíyèsi lónìí.** Àwọn àsàyàn iṣẹ́ ènìyàn, nípasè lílò àwọn epo rọ̀bì (epo, gáàsì àti èédú) àti àwọn ìyípadà lílò ilẹ̀ (pàápàá ìpagbórun), n yorí sí àwọn ìyípadà tí ó kan gbogbo àwọn agbègbè àgbáyé tí ó sì n pọ̀ si.. .

### 3 ÌLỌSÓKÈ NÍNÚ ÀWỌN ÌṢẸ̀LẸ̀ TÍ Ó BURÚ JÙ

**Ipa ènìyàn ti n jẹ́ kí díẹ̀ nínú àwọn iṣẹ̀lẹ̀ tí ó burú jù jẹ́ lóòrèkóòrè, kí ó le sí i, kí ó gùn sí i, tí ó sì n mú ìyípadà bá ìgbà àti àkókò wọn.** Kò sí iyèméjì pé iye àti bí ìgbóná ilẹ̀ àti ìgbì òkun ṣe le koko, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ òjò rírọ̀, ọ̀dá, àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó kan ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àálà wọ̀nyí, ti pọ̀ sí i láti ìgbà àkókò ìṣáájú-iṣẹ́.

### 4 CO2 N ṢÀJỌPỌ̀

**Eyọ tóònù CO2 kòokan tí ó n kún ojú-afẹ́fẹ́ ṣe àfikún sí ìmóruṣi àgbáyé síwájú si.** Tí a bá dẹ́kun àfikún CO2 lónìí, ìwọ̀n òtútù àti ooru àgbáyé yóò dúró ní ìpele tí ó wà lọ́wọ́lọ́wọ́. Bí ìdádúró kábọ̀nù se n pé síi ( àpapọ̀ sí òdo tí ìtújáde CO2 ) bẹ́ẹ̀ni ìpele ti ìmóruṣi n pọ̀si, àti àwọn ewu tó somọ́o. .

### 5 ṢIṢẸ́ NÍ BÀYÍ

**Kódà nínú iṣẹ̀lẹ̀ ìdínkù ìtújáde tí ó jinlẹ̀, kò ṣéése mọ́ kí ìtújáde ma yorí sí itesiwaju ìmóruṣi fún Ogún ọdún tó n bọ̀ àti pé àlà-ìwọn 1.5°C yóò rékọjá ní àwọn ọdún 2030. Ìwọ̀n ìyípadà ojú-ọjọ́ lẹ́yìn 2040 àti àwọn eewu fún àwọn ẹ̀dá abẹ̀mí tó n gbépọ̀ àti àwọn àwùjọ ènìyàn, ní ìdà keji, dá lórí àwọn yíyàn àti àwọn ìgbésẹ̀ ti òde òní.**

### 6 ÀWỌN ÀBÁJÁDE SÁÀ TÓ GÙN PÚPỌ̀

**Àwọn ìyípadà sí àwọn isàn omi ti àgbáyé àti àwọn agbègbè tí ó tutùnini jẹ́ èyítí kò sé yípadà ní ìwọ̀n-ìrandíran, ṣùgbọ́n òṣùwọ̀n wọn se é fà sẹ́yìn nípasè dídín ìmúruṣi kù, èyítí ó ṣe pàtàkì fún ìsàmúbádọ́gba.** Àwọn ìpele ìwọ̀n òkun yóò tẹ̀síwájú láti máa ga síi fún àwọn ẹgbẹ̀rún ọdún àti àwọn yìnyín tó dì yóò tẹ̀síwájú láti máa yọ́ fún àwọn ọdún méwàá, pàápàá lẹ́hìn tí ìmóruṣi àgbáyé bá ti dáwọ́ dúró.

### 7 GBOGBO ÌWỌ̀N ÌDÁMẸ̀WÁ SE PÀTÀKÌ

**Gbogbo àfikún sí ìmóruṣi n tẹ̀síwájú láti mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àyípadà pọ̀ si ní ojú-ọjọ́ wa: àwọn èyí tó ga jù, ìyípo omi, ìwọ̀n gíga sókè ti òkun ní ìbásepọ̀ tààrà pẹ̀lú ìwọ̀n ìmóruṣi.** Afẹ́fẹ́ ooru tí ó ní ànfàní eyokan nínú àádọ́ta láti ṣẹlẹ̀ ní àwọn àkókò ìṣáájú-iṣẹ́ yóò ní ànfàní láti ṣẹlẹ̀ ní ìgbà mẹ́sàn-án ní àkókò 1.5°C ìmóruṣi àgbáyé, àti ní ìgbà mókànlá síi ní àkókò 2°C.

### 8 ÀWỌN OHUN TÍ N GBÉ KÁBỌ̀NÙ MÌ TI WÀ NÍ ÌDÁNWÒ

**Isàn omi àti ojú ọ̀run kó ìdajì gbogbo àwọn ìtújáde CO2 latí owó ènìyàn. Imorusi ti o lagbara julọ yoo din iye kábọ̀nù ti wọn fa kù.**

### 9 GBÉ OHUN GBOGBO YẸ̀ WÒ

**Ani láti gbé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ to ní ànfàní kékeré lati sele wò kí a le gbero imudagbapapo at isiro ewu, nitori won yóò ní àbájáde to le fún ibagbepo ohun abẹ̀mí àti àwùjọ ènìyàn.** Bí àpẹẹrẹ, bí igbó kìjikìji ti Ámásònì ṣe ń yára kú, àwọn ìyípadà tó máa ń ṣẹlẹ̀ lójijì nínú ìyípo isàn omi tàbí yíyọ́ àwọn òkìtì yìnyín. Bí ìwọ̀n ìpele ti ìmóruṣi se n ga si, bẹ́ẹ̀ni ewu ìrú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀..

### 10 ÀWỌN ÀNFÀNÍ TÓ YÁRA

**Àwọn ìgbésẹ̀ tí a gbé láti dín àwọn ìtújáde èéfín gáàsì olóró kù ní àwọn ànfàní ìlera gbogbogbò lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.** R Ìdínkù lílò àwọn epo rọ̀bì mú afẹ́fẹ́ dára sí i. Síwájú sí i, dídín ìtújáde metéènì kù kò wulẹ̀ ṣe ìdiwọ̀n ìmóruṣi onígbà kúkúrú nìkan ṣùgbọ́n ó tún se ti òsóònù ojú afẹ́fẹ́, ìdọ̀tí inú afẹ́fẹ́ tí n ṣèpalára fún ìlera àti èso iṣẹ́ àgbẹ̀.

**Digest co-written by the french collective *Pour un réveil écologique* and authors from IPCC working group 3**

# ÀWỌN KÓKÓ ÒRÒ PÀTÀKÌ 10

## láti ìjábò IPCC tuntun

Ẹgbẹ 2 - Àwọn ipa, aṣàmúbádógba àti àìlágbára

### 1 ÌYÍPADÀ OJÚ-OJÓ TI N NÍ IPA LÁRA ÌSÈDÁ ÀTI ÀWỌN ÀWÙJỌ

Àwọn ipa búburú ti ìyípadà ojú-ojó ni à nṣe àkíyèsi ní àgbáyé. Àwọn eewu tó yára tí ó tí fà ni ó se ìdiwòn ìfaradà tí ó pé fún àwọn ètò wa. Pẹ̀lú ìgbékèlé gíga, àwọn ìwòn òtútù àti ooru tí ó pòsi àti ògbelè lè ní àsopò sí ewu rògbòdìyàn, èyí ni ati lè máa rí télè ní àríwá Nàìjíríà.

### 2 ÌDAJÌ ÀWỌN ÈNIYÀN WÀ NÍNÚ EWU ÌPALÁRA NLÁ

Àwọn táláká àti àwọn orílè-èdè tó sèsè ndagbasoke wà nínú ewu ìpalára ìyípadà ojú-ojó, bótilèjépé díè ni àfikún won sí ìmórusi tó n ṣelè lówólówọ. Ìkójopò àwọn ètò ònà àbáyo tó kóni móra tó dá lórí ìwà òdodo àti ìdájó àwùjọ àti ojú-ojó se ìdínkù sí àwọn ewu àti síse ìrànlówó fún ìdàgbàsókè ìfaradà fún ojú-ojó..

### 3 IPA TÓ N DÀGBÀ TÓ SÌ N SE ÌDÉRÙBÀ NÍ ÁFÍRÍKÀ

Pẹ̀lú pẹ̀lú ìlọsiwaju nínú iṣàmúbádógba, àwọn ènìyàn àti ìsèdá tí n rí ipa télè ní àgbáyé. Àpapò àwọn ìwòn òtútù àti ooru ti pòsi ní ìwòn eyòkan sí méta (1 - 3°C) ní ìwò-òòrùn Áfíríkà ní àkàwé sí àpapò àgbáyé ti 1.1°C. Ìyípadà ojú-ojó ti dín ààbò óúnjẹ kù télè nípasè àwọn àdánù nínú àwọn ìkórè irúgbìn, àwọn agbègbè, òsìn ẹran àti àwọn eja, ìbàjé nínúdídára óúnjẹ, wíwọlé àti pínpín, àti àwọn ìlọsóke iye owó. Ó tún ní àwọn ipa òdì lórí ìlera ènìyàn, àwọn amáyéderùn, agbára, àwọn ohun àmúsorò inú omi àti èto-orò ajé. Àwọn ìṣèlè ojú-ojó ní kóntínèntì mìíràn lè ní ipa lórí Áfíríkà nípasè àwọn ọjà àgbáyé.



### 4 ÀWỌN EWU NÍ GBOGBO ÀWỌN AGBÈGBÈ ÀTI ÀWỌN ÈKA

Àwọn ewu ojú-ojó pò si pẹ̀lu ìpele ti ìmórusi àgbáyé. Méjì nínú àwọn ewu pàtàkì ní Áfíríkà ni àwọn ìṣèlè omíyalé etíkun àti ìjì líle pàápàá ní Nàìjíríà, nibiti omíyalé yóò tí ṣelè sí diẹ nínú àwọn agbègbè Èko fún ìgbà pípé títí. Omíyalé bii awọn tó ṣelè làipé ní Nàìjíríà, ṣeé ṣe láti jé olóòrèkóòrè. Àwọn ewu pàtàkì mìíràn jẹ awọn igbi ooru ati awọn abajade wọn fun eniyan ati ìbágbépò ohun abèmí, ìsírò ikú àti àìlera; Àwọn àdánù ìkórè ìṣé-ògbìn nítorí àwọn ìgbì ooru àti àwọn ògbelè; àìtó omi. Àwọn ewu wònyí pò si ní àwọn agbègbè ìlú àti etí òkun.s.



### 5 ONÍRUURÚ OHUN ABÈMÍ LÁBÉ EWU ÌDÉRÙBÀ NÍ GBOGBO ÀGBÁYÉ

Àwọn ètò ìbágbépò ohun abèmí tí a gbékèlé ti dé ìkóríta àrèmabò, paapaa nitori wahala omi ati awọn igbi ooru lori ilẹ ati ni okun (fún àpẹẹrẹ àwọn òkúta iyebiye abé omi). Títí dé ida Ogún awọn ohun abèmí tí n gbé ori ilẹ ti wa ni ewu iparun ti ìmórusi àgbáyé ti ìwòn 3°C bá dé. Àìlálòpé ilè lílò àti àwọn ohun àmúsorò inú òkun ti n ní ipa ìpanirun lórí awọn ìbágbépò ohun abèmí lórí èyítí a gbékèlé.

### 6 ÒNÀ ÀBÁYO WÀ FÚN ÌṢÀMÚBÁDÓGBA ÀTI WÍPÉ ÌLÒ WON NÍLÒ RÍRÓ LÁGBÁRA

Dídékun ipadanu ati ibajẹ nilo imuṣiṣẹ to yara ti awọn ònà àbáyo ìṣàmúbádógba tí a jèrìí pé ó múnádóko tí yóò sì séése . Ìbágbépò ohun ògbìn, ìṣàkóso igbó, ìṣàkóso awọn ohun àmúsorò inú omi ati ikojọpọ imọ awọn eniyan ìgbèríko lè ṣe ìrànlówó láti dènà àwọn ewu àti láti ṣe ìdánimò àwọn ònà àbáyo tí ó dá lórí àwọn ètò ìbágbépò ìgbèríko.

### 7 ÌṢÀMÚBÁDÓGBA NÌKAN KÒ TÓ LÁTI ṢE ÌDÍWÓ FÚN ÌTÈSÍWÁJÚ ÀWỌN EWU OJÚ-OJÓ

"Àwọn ìdiwòn líle" ti pípòsi omi òkun, àwọn ìgbì ooru àti àwọn ògbelè túmò sí pé ìdádúró àwọn ìtújáde GHG jé ohun pàjáwìrì. Gbogbo ìwòn ìdámèwá ìmórusi àgbáyé jé kí ìṣàmúbádógba túbò gbòòrò síi.

### 8 FÈRÈSÉ FÚN ÌGBÉSÈ TÍ N KÉRÉ SÍ I

Díè nínú àwọn ipa ti ìyípadà ojú-ojó jé èyítí kò lè yípadà. Ìṣàmúbádógba ti ntesiwaju, ṣugbọn ó sì jé aláìpé pátápátá ní ojú ìyípadà tó n yára ṣelè. Èyíkèyí ìdíwó síi lórí ìdádúró àti ifaramo iyipada oju-ọjọ wà ní ewu ìpàdánù ànfàní fèrèsé kékeré láti ní ààbò ojó iwájú alálòpé.

### 9 ÌYÍPADÀ SI ÌDÀGBÀSÓKÈ TI ÌFARADÀ OJU-ỌJỌ LE JẸ ETO LÉSEESE, TÓ KÓNIMÓRA, OLÓDODO ÀTI ỌLÓGBỌỌGBA NÌKAN.

Àwọn ìjọba, àwọn ènìyàn àti àwọn òṣìsé aládàáni se ìdínkù àwọn eewu ní ònà tó múnádóko nípasè ètò ònà ìsàbójútó tí ó kónimóra. Ìyípadà ti o jé olódodo àti ọlógbọọgba n ṣe ìrànlówó fún Ìṣàmúbádógba àti ìdékun, nígbàtí ó n se ìdínkù àwọn àìdógba.

### 10 BAṢEPỌ LAARIN ÒṢÙWÒN ÀYÍKÁ ÀTI ÀWÙJO

Ọpọlọpọ awọn òṣùwòn aṣamubadọgba, fun apẹẹrẹ ti o nii se pelu ounjẹ tabi eto ilu, ṣe atilẹyin aṣeyọri ti awọn afojusun Idagbasoke alalope ti UN: idinku ìṣé, ebi, àìdógba, pipadanu oníruurú ohun abèmí ati ètó sí agbara oní kábònù-kékeré. Ìbádógba ìyípadà ojú-ojó àti ìdínkù èéfín gáàsìi olóró lè jé ìmúdúró fún ara wọn..

Digest co-written by the french collective *Pour un réveil écologique* and authors from IPCC working group 3

# ÀWỌN KÓKÓ ÒRÒ PÀTÀKÌ 10
## láti ìjábọ̀ IPCC tuntun

Ẹgbẹ 3 - ìdínkù ìtújáde

### 1 ÌTOPASÈ ÌTÚJÁDE

Nígbàtí díẹ̀ nínú àwọn orìlẹ̀-èdè ti ṣàṣeyọrí ní ti ìdínkù àwọn ìtújáde orìlẹ̀-èdè wọn àti láti wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìtopasè +2°C, àwọn ìtújáde èéfín gáàsì olóró àgbáyé (GHG) tún n dide síi. Láìsí àwọn ìlànà ojú-ojó tuntun, ìmóru si lè dé ìwọ̀n +2.2 sí +3.5°C ní òpin ogórùn-ún ọdún! Láti jẹ́ kí ó wà ní ìsàlẹ̀ +1.5°C, a nílo láti dín ìtújáde wa kù ó kéré jù ní ìwọ̀n etalelogoji 43% ní ọdún 2030 kí a sí dé ìpele àwọn ìtújáde tí o ga jùlọ ṣáájú ọdún 2025.

### 2 A NÍLÒ ÌGBÉSẸ̀ KÍÁ KÍÁ



A ti wà lójú ọ̀nà tẹ̀lé láti kọjá ìsúná ìwọ̀n kábọ̀nù +1.5°C ní 2030, dá lórí ìdàpọ̀ agbára ti lọ́wọ́lọ́wọ́. Síbẹ̀síbẹ̀ àwọn ìdóko-òwò agbára epo rọ̀bì tuntun tún wà lọ̀ju ọna. **A NÍLÒ LÁTI GBÉ ÌGBÉSẸ̀ NÍ KÍÁ KÍÁ, ti àwọn ilé iṣẹ́ epo rọ̀bì tí ó wà tẹ́lẹ̀ pa kí o sì gbésẹ̀lé ìdóko-òwò epo rọ̀bì.**

### 3 PÍPÍN ÀWỌN ÌTÚJÁDE

Pínpín àwọn ìtújáde ò sí ní ìdógba. Àwọn ida méwàá ọlọ́rọ̀ jùlọ se ìtújáde èéfín gáàsì olóró láàrín ìdá mẹ́rìndínlógójì àti ìdá márùndínláàdọ́ta. Awọn eniyan ti o wa ni awọn orilẹ-ede to ti ni idagbasoke se ìtújáde tóònù mẹ́tàlá ti CO2 láàrín ọdún kan ni apapọ, ní àkàwé pẹ̀lú 1.7 tóònù ní ọdun kan fún àwọn tí ó wà ní àwọn orílẹ̀-èd3 tí kò ní ìdàgbàsókè.

### 4 ÒNÀ ÀBÁYO ÌMÒ-ẸERỌ ÀTI ÌYÍPADÀÀWÙJỌ

Àwọn ìdàgbàsókè ìmò-èro titun tó yára n jẹ́ kí ìyípadà ti agbára séése:










Àwọn ìidojúko jẹ́ ìmò-èro àti ti àfojúrí ṣùgbọ́n pàápàá àti ju gbogbo rè lo àwùjọ àti ìṣèlú nà. Ìyípadà tó jẹ́ ìpìlẹ̀ nínú àwọn yíyàn óúnjẹ si ọna ìdínkù óúnjẹ tó kún fún ẹran jẹ́ àpẹẹrẹ ti ohun èlò tí ó lágbára

### 5 YẸRA / YÍPADÀ / MÚDÁRASI

**Ìlọsíwájú ìmò-èro jẹ́ pàtàkì, síbẹ̀síbẹ̀, kì yóò tó**, ati pe o gbọdọ wa ni abojuto lati **yago fun ipa ipadabọ**. Fún àpẹẹrẹ, ó yẹ kí a yàgò fún ìrìn ọ̀nà jíjìn (nípasè ọkọ̀ òfurufú pàápàá), nígbàtí gbígbé òpọ̀lọpọ̀ ènìyàn, ìrìn-ẹsẹ̀ tàbí gígun kẹ̀kẹ́ yẹ kí a ṣe ojúrere sí. Lákòótán, ìmúdárasi ìṣiṣẹ́ agbára jẹ́ pàtàkì, pàtàkì jùlọ fún àwọn ilé àti ilé-iṣẹ́.

### 6 ÒṢÙWỌ̀N FÚN IṢẸ́

Òkan nínú àwọn òṣùwọ̀n àkókó fún iṣẹ́ jẹ́ **ìyípadà ìgbésí ayé ìgbékalè.** Iṣẹ ènìyàn kòòkan, bótilẹ̀jẹ́pé yóò ní ipa nìkan tí ó bá ní àtìlẹ́yìn ìyípadà lápapọ̀ tó múnádóko. Ìyípadà yìí yóò fa ìdá ogójì sí ààdórin ìdínkù nínú àwọn ìtújáde, ni pataki nipasẹ ipese awọn eto imulo.

*(ṣeto awọn eto imulo ati awọn iṣe ojoojumọ ti o yago fun ibeere fun agbara, awọn ohun elo, ilẹ ati omi lakoko jiṣẹ alafia eniyan fun gbogbo eniyan laarin awọn aala aye)*

*O tun ṣe pataki si:*



- *Dáwọ́ lílò àwọn epo rọ̀bì dúró nipasẹ itanna pọ pẹlu ìyọkúrò kábọ̀nù ninu ina ẹ̀létíríkì*
- *Dá ipagborun dúró kí ó sì mú ìmúpadàbọ̀ ilẹ̀ pọ̀ si*

### 7 YÍYỌ $CO_2$



Ìmúṣiṣẹ́ ti yíyọ CO2 láti san àwọn ìtújáde àlòkù tó sòro láti dínku jẹ́ ẹ̀yítí kò lè ṣàì ṣẹlẹ̀ láti ṣàṣeyọrí lórí dídékun kábọ̀nù ṣùgbọ́n àwọn ìtaláyà nlá wà níwájú (nípasè ìmò-èrọ, ìṣàkóso ilẹ̀, àti gbígbà àwùjọ, láàrín àwọn mìíràn)

### 8 ÀWỌN ÌLÚ

Àwọn ìlú àti àwọn àṣà ìtòlú tó n ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ jẹ́ kókó pàtàkì tó n tukò ìtújáde èéfín gáàsì olóró. A nílo **Iyipada eto léseese fun awọn aṣa itolu wa** ati pe o le din itujade wa kù ni ìdá mẹ́rìndínlógbọ̀n ni ọdún 2030.

### 9 ÌLÀNÀ ÀTI ÈTÒ ÌSÚNÁ

Àwọn ìtújáde àgbáyé tí kò ní ìlànà pò jù ìdajì lo, sibẹ eyi jẹ **kókó pàtàkì ati òṣùwọ̀n tí a kò lò.** Fún àpẹẹrẹ, **ìdíyele kábọ̀nù ti ogórùn-ún owó dólà $100 fun tóònù kan ti CO2** yóò ṣe ìwúrí fún àwọn ìgbésẹ̀ ìdínkù tí ó lè se ìdínkù àwọn ìtújáde àgbáyé ní ìdajì ni ọdún 2030. Ní àpapọ̀, **àwọn ìdóko-òwò lọ́wọ́lọ́wọ́ lórí ìyípadà kò pọ̀ tó.** Ìpèníjà nlá kan yóò jẹ́ láti ṣe àtìlẹ́yìn ìlànà láti lè darí owó tó wà.

### 10 LERA ÈNÌYÀN



GH Ìdínkù GHG tún lọ ní bákanáà pẹ̀lú òpọ̀lọpọ̀ àwọn ìfojúsùn ìdàgbàsókè alálòpé, pàápàá nípa ìlera ènìyàn: atẹ́gùn tó péye fún inú ilè àti ìta gbangba, ìṣípòpadà tí nṣiṣẹ́ lọ́wọ́, àwọn óúnjẹ ìlera, àti àwọn mìíràn.

Digest co-written by the french collective *Pour un réveil écologique* and authors from IPCC working group 3